


# ỌWỌ OSI S'ỌWỌ ỌTUN NI O T'ỌNA

Orilẹ-ede Naijiria yio ṣe iyipo-pada wiwa ọkọ ilẹ lati ọwọ osi si ọwọ ọtun ọna lati ọjọ Aiku, ọjọ keji oṣu kẹrin ọdun ti o mbọ yi (1972).

* Ipinnu yi w'aiye ni ibi ipade pataki kan, eyiti awọn Igbimọ lori irinna awọn ọkọ ilẹ ti agbegbe Iwọ Orun Afrika ṣe ni Monrovia ni ilu Liberia ni oṣu kẹwa ọdun 1961, ninu ipade eyiti orilẹ-ede Naijiria gba wipe ki iyipo-pada wa nipa wiwa ọkọ ilẹ lati ọwọ osi si ọwọ ọtun ọna. Naijiria ati awọn ilu agbegbe rẹ ati pẹlu pe yio ṣe okunfa irin ajo pẹlu gbẹfẹ ati irọrun nipa ọna owo ṣiṣe.

* Bi ilẹ Naijiria ba tete bẹrẹ si iyipada ọkọ wiwa ni ọwọ ọtun ọna yi, ire ati anfani nlanla miran ni yio ri ni ọjọ iwaju.

* Awọn iriri eyiti a ti ṣe akiyesi nipa f'fi "eni-da eni, ọla da ọla" lati ọdun kan si ekeji ti fihan wipe yio pọ ju ti ọpọlọpọ orilẹ-ede miran lọ.

* Alaye tabi ikede yi ni lati jẹki gbogbo enia mọ riri eto yi ati lati ni imọ lori lilo awọn ọna wa ni ọjọ iwaju fun ayipada rere.

* Awọn inawo ti a o ṣe fun awọn ami ti o tọ, ti o si yẹ fun oju ọna gbogbo yio mu anfani nlanla wa lati ni awọn ọna ọkọ ilẹ ti o b'oju mu gẹgẹ bi ti awọn ilu miran gbogbo.









* Ni ọdun kẹta lẹhin ipinnu yi (1964), Igbimọ eto idagbasoke ọrọ aje ti ilẹ enia dudu (Afrika) fi ara mọ aba yi nipa wiwa ọkọ ni ọwọ ọtun ọna. Loni, ti a ba fi oju inu wo o, a o ri wipe ninu awọn ilu pataki-pataki bi mẹdogun (15); ilẹ Naijiria ati Gana ni ko iti ye wa ọkọ ni ọwọ osi ọna. Gbogbo awọn ilu ti o yi orilẹ-ede Naijiria ka ni nwọn si ti nwa ọkọ ilẹ ni ọwọ ọtun ọna.

* Anfani nlanla ti o wa ninu aṣa wiwa awọn ọkọ ilẹ bakanna yi yio tunbọ jẹki ọkọ ilẹ pọ sii tarin ilẹ nṣe ni awọn iye owo ti a ba na lori eto yi nle sii to bi idamẹwa lori ọgọrun.

* Lalai ka ilu Gẹẹsi ati Japan, awọn ilu pataki-pataki miran ti a ma nra ọkọ ilẹ lọwọ wọn, ko nwa awọn ọkọ l'ọwọ osi, bikoṣe l'ọwọ ọtun ọna; eleyi ko si ni fun wọn ni iṣiri lati ma ṣe iru awọn ọkọ ti a nwa ni ọwọ osi ọna bayi, nitoripe ọpọlọpọ orilẹ-ede ni o ti ntẹle aṣa wiwa ọkọ ni ọwọ ọtun ọna bayi.

* Eleyi fihan gbangba wipe ti orilẹ-ede Naijiria ba kuna lati ṣe ayipada yi, iye owo ti a o ma fi ra ọkọ

* Awọn igbimọ ti orilẹ-ede yi yan lori eto iyipo-pada wiwa ọkọ ilẹ lati ọwọ osi si ọwọ ọtun ọna yi, ti fun awọn enia orilẹ-ede yi ni idaniloju wipe ki yio si awọn ohun iṣoro kankan lori eto yi. Gbogbo awọn eto yoku lori alafia tabi awọn ohun miran ti o lee jẹyọ lẹhin ọla ni nwọn si ti mura lati kapa rẹ.

* Awọn Igbimọ yi ni ireti wipe, onikaluku yio ṣe ojuṣe rẹ fun alafia ati idagbasoke orilẹ-ede yi lati ri wipe a ṣe iyipo-pada wiwa ọkọ ilẹ lati ọwọ osi si ọwọ ọtun ọna ni aṣeyọri si rere.

## ỌWỌ OSI S'ỌWỌ ỌTUN LO T'ỌNA

